# AWỌN IBUKUN IHINRERE

**2 Kọrinti 3:1-18; 4:1-16**

**ẸKỌ 395 FUN AGBA**

**AKỌSORI: "Kini iwọ si ni ti iwọ kò ti gbà? njẹ bi iwọ ba si ti gbà a, éhatiṣe ti iwọ fi nhalẹ, bi ẹnipe iwọ kò gbà a?" (1 Kọrinti 4:7).**

**I Jijẹ Iwe Kikà**

1 Apọsteli naa kò beere iwe iyin, 2 Kọrinti 3:1-3; Iṣe Awọn Apọsteli 18:27

2 Ọlọrun ni o n funni ni ọgbọn ati agbara lati waasu Ihinrere, 2 Kọrinti 3:4-6; 1 Kọrinti 3:10; 15:10

**II Iṣẹ-iranṣẹ ti Ẹmi**

1 Iṣẹ-iranṣẹ ti Ofin ni ogo, ṣugbọn ti akoko Oore-ọfẹ tayọ patapata, 2 Kọrinti 3:7-11

2 Sisọ otitọ ọrọ ni ilana Ihinrere, 2 Kọrinti 3:12-14; Galatia 4:16

3 A ká iboju ti igba Ofin kuro ninu Kristi, 2 Kọrinti 3:15, 16

4 Iriran nipa ti ẹmi ninu Kristi mú iyipada wá, 2 Kọrinti 3:17, 18; Owe 4:18; Jakọbu 1:25

**III Wiwaasu Kristi**

1 Ṣiṣe otitọ ni akọmọna awọn alufaa Kristi tootọ, 2 Kọrinti 4:1, 2; Johannu 4:23; Efesu 6:14

2 Ki i ṣe gbogbo eniyan ni a gbala, ṣugbọn gbogbo eniyan ni o ni iru anfaani kan naa, 2 Kọrinti 4:3, 4; Matteu 7:13, 14; Iṣe Awọn Apọsteli 10:34, 35

3 Jesu Kristi ni gbongbo ti iwaasu Ihinrere duro le lori, 2 Kọrinti 4:5-7

4 Wiwaasu Kristi n mu inunibini wa, ṣugbọn ki i ṣe iparun, 2 Kọrinti 4:8-10

5 Awọn alufaa Onigbagbọ ti akọkọ ṣiṣẹ, lai tilẹ mọ igba ti iku-ajẹriku yoo jẹ ipin wọn, 2 Kọrinti 4:11, 12

6 Igbagbọ Ajinde ninu Kristi maa n funni ni iṣẹgun nigba gbogbo, 2 Kọrinti 4:13-16; 2:14

## ALAYE

Ọpọlọpọ ninu awọn alufaa ti Majẹmu Titun ni a ti rán jade lọ pẹlu iwe iyin lori iwa otitọ wọn si awọn ti a rán wọn sí. Gẹgẹ bi a ti le ri i ninu ẹkọ yii, ohun ti a ti n ṣe lati mu ki nnkan rọrun si i wá di ohun ọranyan fun awọn diẹ kan, ani ninu Ijọ Kọrinti. O dabi ẹni pe wọn bá Apọsteli nì wí fun aini iru awọn iwe bẹẹ; ṣugbọn a fi otitọ hàn gbangba pé iduro-ṣinṣin igbesi-ayé Onigbagbọ niyelori ju ohunkohun miiran lọ. Iwaasu Kristi lati ẹnu alufaa tootọ, yoo yọri si iyipada igbesi-ayé awọn eniyan nipa iranwọ Kristi eyi ti yoo mú ẹri gbigbona jade ju ọ̀pọlọpọ episteli ti a kọ akọsilẹ wọn. "Ẹnyin ni iwe wa, ti a ti kọ si wa li ọkàn, ti gbogbo enia ti mọ̀, ti nwọn si ti kà."

### Awọn Alufaa Ode-oni

Awọn alufaa ti igba Majẹmu Laelae gbọdọ ni ẹri ti yoo fi hàn pe wọn jẹ́ idile Aarọni tabi Lefi ki wọn to ni ẹtọ lati ṣiṣẹ isin ninu Agọ. Ni ọjọ oni a n yan awọn alufaa Ọlọrun laaarin awọn ẹgbẹ Onigbagbọ́. Ko ṣẹṣẹ digba ti eniyan ba ti idile pataki tabi ẹgbẹ pataki kan wá, ṣugbọn eniyan gbọdọ jẹ ipè Ọlọrun ki o si kún fun Ẹmi Ọlọrun ni iwọn bi o ba ṣe e ṣe lati ni in pọ̀ tó ninu ọkàn rẹ̀ ati igbesi-ayé rẹ̀. Ọlọrun yoo ran iru ẹni bẹẹ lọwọ lati jade lọ; pẹlu irugbin iyebiye Ọrọ naa, bẹẹ ni yoo si so eso Ihinrere ni igbesi-ayé awọn eniyan. Gbogbo iwe iyin ayé yii kò tó lati gba ọkàn kan là, bẹẹ ni ọkàn kan kò si le ni igbala lai jẹ pe Ọlorun ba fún ọkan naa ni oore-ọfẹ ati iranwọ.

Apọsteli yii mọ otitọ yii dajudaju. "Ki iṣe pe awa to fun ara wa lati ṣirò ohunkohun bi ẹnipe lati ọdọ awa tikarawa; ṣugbọn lati ọdọ Ọlọrun ni tito wa." Awọn ibukun Ihinrere pese tito fun olukuluku ọmọ Ijọ Kristi ti a gbala. Ni jijẹ́ iwe kikà, olukuluku le jọwọ ara rẹ̀ ni lilo fun Kristi fun igbala awọn

ọkàn miiran. Jijẹ́ olooотọ ninu awọn nnkan keekeekee maa n fun ni ni iṣẹ titobi ati ojuṣe nlá nlà to bẹẹ ti ki yoo fi si opin fun oriṣiriṣi iṣẹ ti oloootọ ọkunrin tabi obinrin le ṣe fun Kristi.

**Ogbologbo ati Titun**

Pupọ ninu awọn Ọmọ Israẹli ni kò le gba ero yiya kuro ninu Ofin laaye, ṣugbọn, ninu ẹkọ yii Ẹmi n fi idi pupọ hàn ti Majẹmu Laelae ṣe fi aaye silẹ fun Majẹmu Titun. Bi o tilẹ jẹ pe ti lailai ni ogo, sibẹ o jẹ́ iranṣẹ ikú. "Ṣe tabi ki o ku" ni ofin rẹ̀, bẹẹ si ni lai si igbagbọ́ ninu Ọlọrun, kò ṣe e ṣe lati gbé igbesi-ayé ti o bá Ofin mu. Ni ti Ihinrere, ofin rẹ̀ ni "Wo o ki o si yè." Igbagbọ́ ninu Ọlọrun ṣi jẹ lilo sibẹ, ṣugbọn ibẹru ikú ni a mú kuro nitori a ti wẹ oró ikú, ani ẹ̀ṣẹ mọ́ kuro ninu ọkàn nipa igbala. Ihinrere n gbin ireti aaye ti ajinde sinu ọkàn. Awọn eniyan ti wọn ti fi gbogbo ọjọ ayé wọn wà ninu ide ibẹru ikú, maa n ri ara wọn ni titu silẹ lojiji. Ki ni ṣe ti ẹni ti a ti gbala yoo fi maa bẹru ikú, nigba ti ikú jẹ́ kẹkẹ ti yoo gùn lọ si Ọrun?

**Iwe ti Ọlọrun Kọ**

Ika Ọlọrun ni o kọ Ofin sara awọn walaa okuta. Oluwa kọ Ihinrere sara ọkàn ẹran eniyan. Ifẹ gbọdọ wà ninu ọkàn eniyan lati ri i pe Ọlọrun kọ Ọrọ Rẹ̀ sinu ọkàn oun, dajudaju Oluwa yoo ṣe eyi. Ọpọlọpọ awọn eniyan ti wọn ṣẹṣẹ ni iyipada ọkàn ni wọn ti jẹri pe, ni akoko ti wọn wà ninu aini, Oluwa fun wọn ni ẹsẹ Iwe Mimọ́ kan, lẹyin naa wọn si wá bá ọrọ naa pade ninu Bibeli. Sibẹ, niwọn igba ti aaye wà, ti anfaani si ṣi silẹ, a gbọdọ lo gbogbo anfaani ti o ṣi silẹ lati kọ́ Ọrọ Ọlọrun. Alabukun fun (tabi ibukun) ni fun ọkunrin naa ti "didùn-inu rẹ̀ wà li Ofin OLUWA; ati ninu ofin rẹ̀ li o nṣe aṣaro li ọsan ati li oru" (Orin Dafidi 1:2).

Awọ oju Mose n dán nigba ti o pada dé lati ọdọ Ọlọrun nibi ti o gbé lọ gba awọn walaa okuta. Lati igba de igba ni a n ri awọn ọkunrin alagbara ninu Ọlọrun ni akoko Majẹmu Laelae, ṣugbọn ni igba pupọ ni iwa-bi-Ọlọrun ninu ọkàn ọ̀pọlọpọ awọn eniyan naa kò to nnkan rara. Labẹ Majẹmu Ihinrere Oluwa n mu ki o ṣe e ṣe pe ki olukuluku Onigbagbọ́ jẹ́ imọlẹ didán ti n tàn. Jesu ni imọlẹ ayé, Imọlẹ otitọ, "ti ntàn mọlẹ fun olukulùku enia ti o wá si aiye" (Johannu 1:9). Jesu sọ ni ti awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ pe: "Ẹnyin ni imọlẹ aiye. Ilu ti a tẹ̀do lori òke ko le farasin" (Matteu 5:14). Awọn ibukun Ihinrere pese oore-ọfẹ kikun fun ẹnikẹni ti o bá fẹ́; "Ki ẹnyin ki o jẹ alailẹgàn ati oniwa tutu, ọmọ Ọlọrun, alailabawọn, larin oniwà wíwọ ati alarekereke orilẹ-ede, larin awọn ẹniti a nri nyin bi imọlẹ li aiye" (Filippi 2:15).

**Iboju Kuro**

Ẹru ba awọn Ọmọ Israẹli lati sunmọ Mose nigba ti awọ oju rẹ̀ n dán. Nitori ki awọn eniyan le sun mọ tosi ki wọn si feti si awọn ofin Ọlọrun, Mose fi iboju bo oju rẹ̀; ṣugbọn Iwe Mimọ sọ funni pe iboju naa kò ṣi kuro lẹyin ikú Mose. Kika Majẹmu Laelae tun di iboju; oju inu awọn eniyan naa fọ́. Jesu Kristi ti ká iboju naa kuro fun gbogbo awọn ti wọn gba Ihinrere gbọ́. Iriri ti awọn eniyan ri ti fi otitọ yii hàn. Ọpọlọpọ ti du u lati ka ati lati ni oye Majẹmu Laelae ati Ofin ki wọn to ni igbala, ṣugbọn wọn ri i pe wọn kò ni òye Iwe naa. Nigba ti Jesu dé ti O mú igbala wá, awọn eniyan ri i pe Ẹmi ṣi ọkàn wọn O si fun wọn ni oye Majẹmu Laelae ati ti Majẹmu Titun bẹẹ gẹgẹ. Eyi ti ṣe ri bẹẹ? Jesu ni imuṣẹ gbogbo aworan ati ojiji Majẹmu Laelae. Awọn ileri ti igba Laelae pada di imuṣẹ ni akoko Majẹmu Titun.

Gẹgẹ bi imọlẹ oṣupa ati ti awọn irawọ kò ti wulo ni ọsan gangan, bẹẹ gẹgẹ ni imọlẹ Ofin, bi o ti wu ki o logo to ki o si wulo to ni akoko ti rẹ̀, kò fi bẹẹ mọlẹ labẹ imọlẹ nla ti Ihinrere. Ofin jẹ́ Olukọni lati mú awọn eniyan wá sọdọ Kristi, bẹẹ si ni Jesu jẹ Olukọni Nla ti n fi ọna si iye ainipẹkun hàn. Jesu n fun ni ni oore-ọfẹ ti o n ran ni lọwọ lati tẹle E, "ọ̀na, otitọ, ati iye. Gbogbo eniyan le "jù ẹniti o ṣẹgun lọ nipa ẹniti o fẹ wa" (Romu 8:37).

**Ominira**

"Nitorina ẹ duro ṣinṣin ninu omnira na eyiti Kristi fi sọ wa di omnira, ki ẹ má si ṣe tún fi ọrùn bọ àjaga ẹrú mọ́" (Galatia 5:1). Isinru? Bẹẹ ni, nitori a ti kọ ọ pe: "Ifibu ni olukuluku ẹniti kò duro ninu gbogbo ohun ti a kọ sinu iwe ofin lati mã ṣe wọn" (Galatia 3:10). Labẹ Majẹmu Laelae, a de awọn eniyan mọ Ofin, ṣugbọn wọn n wá idasilẹ. (Wo Romu 7:22-24). Ihinrere ti Oluwa Jesu Kristi ti mú idasilẹ yii wá. Idasilẹ kuro ninu ide ilana eto isin ti awọn Ju, idasilẹ kuro ninu ide ẹ̀ṣẹ, idasilẹ kuro ninu

ibẹru ikú nipa mimu ẹ̀ṣẹ kuro, gbogbo iwọnyi si ṣe e ṣe nipa ominira ti Kristi mú wá. Nigba ti awọn eniyan bá gbagbọ́, ti wọn gbọran, ti wọn si fẹran Olugbala, lẹsẹkẹsẹ, wọn a si di alajọpin awọn ibukun iyebiye ti Ihinrere. Kò ṣoro lati mọ̀ pe Ihinrere ṣanfaani ju Ofin ati gbogbo èto rẹ̀ lọ.

Onigbagbọ́ ki i gbé igbesi-ayé ti kò nilaari. Anfaani ti o tó wà ninu Ihinrere Oluwa fun igbesi-ayé ẹkunrẹrẹ ti o jinlẹ ninu ifẹ Ọlọrun. Nigba ti eniyan ba la oju silẹ, (ṣi ọkan payá) ti o ba si wo ogo Oluwa tọkantọkan, yoo ni iyipada si aworan ti Oluwa gan an, lati inu ogo de inu ogo. Eyi ni ohun ti Oluwa maa n ṣe fun awọn eniyan Rẹ̀. O ma n mu wọn dabi Oun tikara Rẹ̀ siwaju ati siwaju.

**Ihinrere ti O Farasin?**

Pẹlu gbogbo aapọn, aiṣaarẹ, igbiyanju awọn iranṣẹ Ọlọrun tootọ ninu Ihinrere, pẹlu gbogbo jijẹ olootọ Ọlọrun ati ainifẹ Rẹ̀ si pe ki ẹnikẹni ṣegbe, ki i ṣe gbogbo eniyan ni a o gbala. Bawo ni eyi ṣe le jẹ́ otitọ? Ọlọrun n tan imọlẹ fun olukuluku ẹni ti o wá sinu ayé. Imọlẹ tootọ ti wá sinu ayé, ṣugbọn awọn eniyan fẹran okunkun ju imọlẹ lọ, nitori ti iṣẹ wọn buru. Ni gbigbe inu okunkun pẹlu kikun fun iṣẹ buburu, awọn eniyan ti di ijẹ fun eṣu ẹni ti i maa fọ́ oju inu awọn ti kò gbagbọ, ki imọlẹ Ihinrere ologo yii ma ba tàn si wọn. “Bi ihinrere wa ba si farasin, o farasin fun awọn ti o nù.”

Irin pẹlẹbẹ funfun ti a fi n ṣe ikoko afuyẹ jẹ́ irin ti o wọ́pọ̀ jù lọ ninu ohun ti a n wà lati inu ilẹ, sibẹ eniyan gbọdọ walẹ kàn án, ki o ṣiṣẹ lori rẹ̀ ki o to le ri ère rẹ̀ ni kikún. Bẹẹ gẹgẹ ni o ri nipa ti Ihinrere: bi ẹnikẹni ba n fẹ ni in, o gbọdọ wá a ki o si lo igbesi-ayé rẹ̀ gẹgẹ bi ẹkọ rẹ̀, ki o ba le ni ibukun Ihinrere ni kikun. Ihinrere kò farasin rara fun ẹnikẹni ti o ba fi tọkan-tọkan wá a.

**Iṣẹgun**

Ki i ṣe igba gbogbo ni oju ọna maa n jọ̀lọ fun awọn ọmọ Ọlọrun ninu irin-ajo wọn, ṣugbọn biba Kristi rin maa n mu ibukun wá ni gbogbo igba. Apọsteli ni jẹwọ pe oun jiya, nigba gbogbo ni oun n yọ ayọ iṣẹgun ni opin rẹ̀. Igboya nlá nlà kan ti o si ṣe iyebiye ju lọ maa n wà ninu ọkàn Onigbagbọ tootọ: ani ireti ajinde. Lai ka ohunkohun ti o le ṣẹlẹ si ara kiku wọnyii sí, ohun gbogbo yoo yọri si rere ni igba ajinde nigba ti aiku yoo dipo kikú. “Nitori eyi ni ãrẹ̀ kò ṣe mu wa; ṣugbọn bi ọkunrin ti ode wa ba nparun, sibẹ ọkunrin ti inu wa ndi titun li ojojumọ́”.

## AWỌN IBEERE

1 Ki ni ṣe ti Apọsteli naa kò wá iwe iyin?

2 Ara ki ni a kọ Ofin Mẹwaa sí?

3 Ara ki ni a kọ Ihinrere sí?

4 Ki ni ṣe ti Mose fi iboju bo oju rẹ̀? Bawo ni a ṣe lo apẹẹrẹ yii lati fi ṣe apejuwe kika Ofin Mose?

5 Ọna wo ni o gba ṣe e ṣe ki Majẹmu Laelae pada di Iwe ti o ṣí silẹ?

6 Bi Ihinrere ba farasin, ta ni o farasin fun? Ki ni ṣe?

7 Ki ni gbọdọ jẹ kóko iwaasu Onigbagbọ́?

8 Ipo wo ni ireti ajinde kó ninu ọkàn Onigbagbọ́?